# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

## KINI OKE BALẸ FI ṢE IGBIMỌ OSHOGBO

Inu mi yio dun pupọ ti ẹ ba le gba mi laye lati bere lọwọ awọn Igbimọ Ilu Oshogbo, ohun ti o fa a ti nwọn ko fi ni itara ninu ọran ti o ba kan awọn Adugbo Oke- Balẹ.

Nigbati awọn Igbimọ Ilu nfun gbogbo Adugbo ni nọmba (number), si ile wọn lati ma a fi gba iwe (letter) nwọn da Adugbo Oke-Balẹ si.

Nisisiyi nwọn si tun fẹ berẹ Omi-ẹrọ lati ma a fun gbogbo Adugbo, a ko iti ri apẹrẹ pe nwọn a fun Adugbo Oke-Balẹ, Kini ṣe?

Inu mi yio dun pupọ ti awọn Igbimọ Ilu Oshogbo ba le fi eyi si ero ki nwọn si ma a ṣe eto idagbasoke Ilu fun gbogbo Adugbo bakanna, ki o ma a ba a si ikun sinu nipa owo ori, nitoripe gbogbo Adugbo ni o nsan an bakanna. Mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi yi.

Emi ni,
J. O. P Owoborọde
OSHOGBO.

## ALAYE KUKURU FUN AWỌN OLUBERE

Olotu, jọwọ gba mi laye diẹ lati ṣe alaye kukuru fun awọn olubere nipa ibere wọn ti o njade lọsọsẹ. Bi ẹnikan ba bere ọrọ kan, ti nwọn si dahun rẹ o yẹ ki ẹniti o bere yẹn le sọ ẹniti o ba jana, nitoripe ẹlomiran le sọ wipe bẹni, ẹlomiran si le sọ wipe bẹkọ. Nitori idi eyi, a fẹ ki Olotu ba wa fi lọ fun gbogbo awọn olubere ki nwọn ma a tẹle ọna yi.

Bi o tilẹ jẹ wipe nwọn ti ṣe alaye yi lẹkan ri, ṣugbọn sibẹsibẹ a ko tẹle ọna na rara. Tabi bi olubere na ko ba mọ ẹniti o jana, ki o bere lẹdọ awọn agbalagba ki nwọn sọ fun un. Lẹhin na ki o wa sọ ẹniti o ba jana. Mo rope iru ọna yi yio mu iṣiri wa fun awọn oludahun na pẹlu.

Mo dupẹ o Olotu, ọwọ yio ma a roke fowo, fẹmọ ati fun alafia aṣẹ.

Emi ni.
Sam Jẹwọ Ṣangodare
AWẸ.

## KINI FA WỌNYI?

Olotu jọwọ gba mi laye diẹ ninu iwe rẹ Oloyinmọmọ lati ṣe abere awọn ọrọ wọnyi, lọwọ awọn ọrẹ mi to nka Iwe Irohin Yoruba, nitoripe awọn Baba wa ni ma a npa lowe wipe bere-bere ki ṣi bere.

1. Kini fa tojẹ gbogbo awọn ọmọ wa lọkunrin tabi lobinrin lodi ọmọ-Alaigbọran to bẹ ti ẹnu Iya tabi Baba ko nka wọn mọ?

2. Kini ṣe ti awọn ọmọ-birin wa fi tete nlọ si Ile ọkọ lasiko yi ju ti igba laš-lai lọ?

3. Kini fa airi iṣẹ ṣe awọn ọdọ-mọdekun-rin ni asiko yi?

4. Kini fa ọwọn onjẹ nilẹ Yoruba?

Emi ni,
E. O. Sawyerr
MINNA.

## KINI IGBADUN IROHIN YORUBA?

Olotu Inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le gba mi laye lati bere ọrọ wọnyi lọwọ awọn ti o nka iwe rẹ oloyinmọmọ.

1. Kini ṣe ti a fi ni Iwe Irohin ni ede Yoruba?

2. Kini ṣe ti awa ọmọ Yoruba fi nkọ Yoruba si i?

3. Iru iranlọwọ wo ni Olotu Iwe Irohin Yoruba nṣe fun awa ọmọ Yoruba?

4. Kini anfani ti o wa ninu iwe Irohin Yoruba kika nigba gbogbo?

Inu mi yio dun pupọ bi awọn ọmọ Yoruba ba le la eyi ye mi ni kikun fun idagbasoke orilẹede wa, Olotu mo dupẹ o.

Ẹmi ni,
L. S. Ṣoaga
Arinlẹṣẹ Post Office
ABẸOKUTA.

## ITUMỌ ADITU ỌRỌ MI NI YI

Nipa Aditu ọrọ ti mo fi sọwọ si Olotu, ti o si tẹ jade ni oju ewe kẹta ninu iwe ti ọjọ kẹsan oṣu kẹwa ọdun yi pe ki ẹnyin onkawe Irohin Yoruba o fi ye mi, nipa awọn idajọ ti nwọn ṣe fun awọn meji ti o pa enia pe ti nwọn ba le ṣe nkan bayi-bayi nwọn a fi wọn silẹ, o dun mi pe a ko ri ẹniti yio dahun, Itumọ na niyi:-

Ẹnikini sọ fun Adajọ wipe ti awọn paapa ti o da ẹjọ fun on ba le ṣe ohun ti nwọn wipe ki on ṣe, ti on si ri tiwọn gẹgẹ bi apẹre lati le fi ṣe bẹẹ on o si ṣe e gẹgẹ bi nwọn ti bere pe ki on o ṣe e, Ẹnikeji paapa si tun sọ bi ẹnikini ti sọ ni nwọn ba fi awọn mejeji silẹ.

Emi ni,
R. A. Owolarafẹ
Shop Keeper
ỌYỌ.

## IRU ẸDA WO NI AWỌN MẸTA YI?

Olotu--Ẹjọwọ mo tọrọ aye diẹ lati jẹki ibere mi yi o jade, awọn Ẹda mẹta kan wa, ekini ni ti o ba bi ọmọ yio fa a sita yio dumbu rẹ, ekeji ti o ba bi ọmọ yio fa a lọ si ọja lọta, ẹkẹta, ọrọ ọlọrọ ti ko mọ idi rẹ ni i ma a da si ki ri.

Ẹ jọwọ ẹnyin onkawe wa iru Ẹda wo ni awọn mẹtẹta yi o?

Inu mi a dun pupọ ti ẹ ba le tete fi itumọ aditu-ọrọ yi ye mi.

Emi ni
Salawu Barber Ẹdẹ
c/o Tiamiyu Ọmọtọṣọ Ẹdẹ
ILỌRIN.


## Abiyamọ! "Bamwo" De!! Alajela Omode!!!




Idera ati alafia de! Ko si ibanujẹ ati aisun mọ. Angẹli olutoju ọmọ rẹ ti mu ẹbun kan wa fun u lati ọrun wa. "BAMWO" ni orukọ ẹbun na. O dara pupọ fun Inu-iwọ, Iso tabi ṣgufẹ, Iba, Igbona, Eyi, Ailesun, Ibinu-sodi ati orisirisi aisan miran ti o ma nṣe omode lakoko ehin hihu. Dan igo kan wo, iwọ yio si ri pe o dara ju eyikeyi ninu awọn ogun ti o ti nlo fun ọmọ rẹ lọ. Igo kekere 2s 6d; igo nla 4s 6d. Owo ọkọ, 1/-.

### The Egba Trading Aradan Stores

144, Denton Street, 18 Denton Bridge Street, P. O. Box 2, Ebute-Metta. Phone 569. A tun wa ni New Motor Park, Ogunpa Ibadan.



### ABIYAMỌ ETI RẸ MELO!

Abiku ọmọ nda ọ l'amu bi?

Awọn arun wọn yi ha nyọ ọmọ rẹ l'ẹnu bi?—

AIPERI
ỤRẸRẸ
INU-IWỤ
OSI
IGBONA
IKỤ
IGBẸ-ỤRIN
OTUTU
IBA
JẸDIJẸDI

ati orisirisi awọn arun miran ti Ima yọ ọmọde l'enu ni igo BHIN-HI-HU. Lọ ra "YARO" awo igbe arun ọmode ni fun gbogbo awọn ara ti Ima yọ ọmọde l'ẹnu.

"YARO" so pe meji ni gbogbo Ilẹ Nigeria.

Ki iwọ ki o ri i pe oruko "YARO" ni o wa lara igo na ki a ma ba ta adamọdi egbogi miran fun o.


## ỌMỌLARA ỌRUN RERE

KATCHA—Ni ojiji ni a ri iwe gba pe Iya oninure Ọmọlara ti iṣe Iya Amos Idowu Ile Agbero ṣe alaisi ni ọjọ kerinlelogun oṣu kọkanla ọdun to kọja.

A ki awọn ọmọloku ni ile ati ni Oke Okun ki Oluwa tẹ iya si afẹfẹ rere o amin


*FUN ILỌSIWAJU*

POLOWO ỌJA NYIN

SINU IWE

IROHIN YORUBA

